# EJO ALABI AJ'OMOGBE DI KOTU GANRAN



STANDARD SIZE 4D NEW KING SIZE 5D.
See you pay the correct price.

ELETI ỌFẸ
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ



AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hiku-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St. LAGOS

VOL. No. VIII 482. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, AUGUST, 25, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Ejo Alabi Aj'omogbe Di Kotu Ganran

Ejọ Lamidi Alabi elenmọ ara ilu Ilọrin ti o lọ ji awọn ọmọde'kunrin mẹta gbe ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu tokọja pari ni Kotu kekere, (Sant Anna Court No. 2) ni ọjọ Jimọ, 17th August, 1956. Adajọ si fna'sẹ ẹjọ rẹ si Kotu Ganran (Lagos High Court) nibiti biriki gbe dun'lẹ,

Awọn ọmọ ti Alabi elenmọ na ji gbe ni ẹ nwo aworan wọn ninu iwe wa yi, Ganiyu Adisa-ọmọ ọdun mẹrin, Musibau, Amusa-ọmọ ọdun mẹta-abọ ati Asani Babatunde Afoke Ọmọ-ọdun mẹta. Ki adajọ to gbe ẹjọ rẹ lọ si Kotu Ganran, Alabi elenmọ sọ wipe on ko ni pe ẹnikẹni wa jẹri on, bẹni on ko ni sọ ọrọ kan titi ti on yio fi de Kotu nla.



Gauiyu Adisa.

Nigbati Adajọ gbọ gbogbo ọrọ ẹri awọn ẹlẹri ijọba tan, o wipe on gba pe ọdaran na lo ṣe iṣẹ buburu yi, ẹjọ rẹ di Kotu nla, atipe ki nwọn fi si itimọle titi ti ao fi ṣe ẹjọ rẹ ni Kotu Ganran.



Musibau Adio.

Lamidi Alabi ọdaran yi ke ninu apoti wipe on ko kọ lati ṣe ogun ọdun ni itimọle. Oju ẹlẹgba ọkunrin elenmọ na ni ẹ nwo ti nwọn fi ọwọ gbe ori rẹ sok'e yẹn.



Babatunde Afoke.

Awa ṣe aniyan wipe o to akoko ti ijọba ni lati ba wa mojuto awọn ọdẹlẹsinrin ti o nji ọmọ gbe kakiri nwọnyi. Nigbati oju koiti la ni agbọ wipe ko si ifọkanbalẹ nile ati l'oko.

Nigbani, a gbọ wipe bi ẹnikan yio ba lọ si ode, yio dira ogun, lorișiriși bi ada, Kumọ, egbogi, Kondo, atare.

Kanna-kanna, nitori ijaiya awọn ti o nda ọna lati mu enia fi ṣe



Lamidi Alabi.

ẹru, amu lọ ta fun awọn aguda, latigba ti ogun ti pari ti ọtẹ ti buṣe, a ko gburo iwa bẹ mọ.

Aja ha le pada ma jẹ eebi rẹ ndan ?.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ si Ọna owo lati ilu Okere wa Baksnna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si ngbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at:-
A. B. AKINYEMI
10A Moloney Bridge
LAGOS.

## Omo Niyi Eni

EKO Lọjọ 19th ọṣu July 1956, ni Ọgbẹni Adewoye ko ọmọ ti iyawo rẹ Rahamọtu Akanke bi fun jade. Gbogbo awọn ẹbi ati ara lo nawo-nara nibi ikomọjade na.

Awọn alufa ati awọn Alhadji gbogbo wọn lo pejú-pẹsẹ sibi ikomọ ra. Pataki ninu awọn Alufa omo ilu wa to wa sibẹ ni Alufa Salami Akọṣile Ara ilu Ọtun Oro, on l'ẹniti o ke wutuba fi sọ ọmọ na l'orukọ yi wipe Sikiru Rotimi Adewọye.

Ọgbẹni Suberu Kọlawọle nawo pupọ, a ko tilẹ mọ iyatọ larin on pẹlu baba Ikoko–tapẹ na nitori bi Adewọye ti nnawo ninu apo ẹwu, bẹni Kọla nyọ tirẹ ninu Ṣokoto

Arẹmu Adeleko ni onilu ọjọ na, o fi apala rẹ dabira.

Nigbati Yusufu Bandele ati Oyindaye Arẹtọla bọ si agbo nṣ: ni ijo na rinlẹ ti awọn olowo nyọ owo lati fi yẹ wọn si.

Diẹ ninu awọn enia pataki to wa sibẹ ni Ọgbẹni Jinadu Ọlatunji ti o nṣe Baba ẹgbẹ fun awọn ọmọlolaiye. Abdulai Olori, J.O. Kadiri, Suberu Akano Gbẹndu Owo, Ganiyu Alabi, S. Yusufu L. Oyeniyi J. Ẹkundayọ, Adeyẹmi Tailor, ati Alago.

Ire ọmọ yio kari gbogbo wa o.

## Awon To Se Orire Ni Malta Niwonyi

No. 306600 Ani Emeka jẹ £200 ara Enugu
676931 Anyakaoha Ora jẹ £50 Aba
020003 J.E. Peters Okeado jẹ £25 Ibadan
590612 Love jẹ £25 Agbor
006568 Nchekwube jẹ £25 Aba

Iwọnyi ni awọn ti o ngbe ilẹ Nigeria ti nwọn si ṣorire ninu ere ẹṣin ti nwọn ṣe nilu Malta n nu oṣu June Awọn ti number tikiti wọnyi bawa lọwọ rẹ ki nwọn magbar di lati gba owo gọbọyi ti akọ soke yi.

## Alufa gba Alufa leti

EKO. Lọjọ kan ninu oṣu May 1956, nigbati Alufa Lamidi nṣe wasi lọwọ ni ọja Idunmagbo, bẹni Alufa kan de, ti a npe ni Abudu Mọjidi, o si gbe igbati le Alufa Lamidi ti o nṣe wasi, o si da alafia ibẹ ru, ija ọjọ na pọ lobẹ, ti nwọn ni lati gbe Alufa Oniwasi na lọ si ile Alaisan.

Nigbati ọrọ na de'waju adajọ, ti ẹni kini r'ojọ, ti ẹni keji ro tan, ni adajọ ba bẹrẹ si sọrọ yi wipe:- Iwọ Alufa Abudu Mọjidi, o dami loju wipe iru awọn enia wuru-wuru bi tirẹ yi lo fa sababi ẹjọ Apalara, eyiti odogun ohun ti a ni lati yegi fun awọn enia mọkanla. Alufa gẹgẹbi tirẹ gboju - gbaiya wọ agbo ti nwọn nsọrọ Ọlọrun lati lọ gba alufa bi tire loti. Iru iwa yi ko tọ si ọ.

Mo lero wipe iru ẹjọ gẹgẹbi ti Apalara yẹ ki o ti kọ ọpọlọpọ awọn Imale l'ẹkọ, bakanna gẹgẹbi tirẹ yi ni ẹjọ Apalara ti ṣe bẹ sile. Nigbẹhin gbogbo ọrọ yi, adajọ sọ fun Alufa Abudu Mọjidi wipe, iwọ ti jẹbi ninu ọrọ ti o dele yi, nitorina, ki o sare lọ si ẹwọn oṣu mẹfa na a ki o bọ pelu iṣẹ aṣẹṣẹbadi.

O dabi ẹnipe orukọ nro Alufa Mọjidi ni, nitoripe bi enia ba ri irisi oju alufa Mojidi onijọngbọn yi. mọjidi-mọjidi ni gbogbo rẹ ri. Aboju ba ọmọ l'ẹru enia ni. Awọn to nko abuku ba alufa Imale ni iru awọn wọnyi.

## Bawo lao ti se tu ofo yi o Jonmo?

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ṣe ibere yi lodọ awọn ọkowe re. ẹniti o ba le sọ, ki o kọwe si wa fun ọna ti a le gba tu'fọ na oluwa rẹ yio gba ẹbun.

Ibere na niyi:-

Obinrin kan wa, ti o bi ọmọ ọkunrin kan, iṣẹ si gbe ọmọ na lọ si idalẹ. Lẹhin ti ọmọ na lọ si idalẹ tan ni iya rẹ ṣe amodi ti eti rẹ di, ti ko gbọrọ mọ. oju rẹ si tun fọ, ko riran mọ. Lẹhin amodi yi ni ọmọ na ku ni idalẹ. Ohun ti a fẹ mọ niyi. Bawo ni ao ti ṣe tu ọfọ yi fun iya na ti yio fi mọ wipe ọmọ on ku?

Ọmọ Adumila

Eko.

## EHIN DIDUN PELU IRORA

Ọna bibọ lọwọ irora ?
Njẹ iwọ mọ pe ọkan ninu ohun ti o fa sababi ẹhin didun ni Kidinrin ?

Bi ohunkohun ko ba ṣe Kidirin wa nwọn a ṣe gbogbo eri kuro ninu ẹjẹ ki gbogbo ẹya ara wa le ma ṣiṣẹ dede nigbati Kidinrin wa ba nṣe tikọtikọ, ti ko si ṣiṣẹ dede, gbogbo eri a wọjọ sinu ẹjẹ a si ma a mu ki ẹhin dun ni.

Egbogi onirọdorodo fun gbigbemi ti Ọgbẹni De Witt ṣe jẹ egbogi atata ati atamatase ti o nmu ki ẹhin didun salọ kiakia nipa titun ẹjẹ ṣe ati nipa mimu irora ati alafia ba ẹnikẹni ti ẹhin didun na mba ja

O san ki ẹniti ẹhin didun mba ja tete fi egbogi ti a nsọrọ rẹ yi ko loju fun ati ba le jẹ igbadun aiye jupe ki a fi dagunla ki o si ma di ẹnibẹ lọwọ lenu iṣẹ rẹ ati ni igbesi aiye rẹ.

Egbogi De Witt jẹ egbogi ti a ti nlo lati aiyebaye wa, titi o fi di oni yi ko mba wiwo ẹhin didun san ti, ẹgbagbeje enia ti o ti lo De Witt lo nkan sara si fun jijẹ bi idan rẹ. Nitori idi eyi, ogunlọgọ iwe ni nwọn kọ ṣọwọ siwa lati fi dupẹ fun ore ribiribi ti De Witt nṣe fun wọn. Lọ siie tita egbogi ki o lọ ra tirẹ loni fun lilo nitori ijafa lewu.



A se De Witt's Pills nipataki fun Wiwo ẹhin didun, irora orikerike, latanlatan, ibadi sisan.

A fọwọ sọya pe De Witt's jẹ ojulowo egbogi, gbogbo ohun elo ti a si fi se lo pe perepere ti awọn alaṣẹ ilera si kan sara si pe ko si kolofin kankan nipa rẹ.



**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles

No. 73/s.2/vol. VII/248.

## Medical Department, Western Region Vacancies For Clerical Officers.

Applications are invited from suitably qualified Candidates of Western Region origin for appointment in the Medical Department of the Western Region as Clerical officers.

Scale of Salary:- D1,2,3.
£150 x 6 - 162 x 18 - 180 x 9 - 234 x 12 - 330 x 15-360.

For full particulars see Western Regional Notice No. 669 in Western Region Gazette No. 42 of 16th August, 1956,

Closing date 20th September 1956.



**Ehin l'o ndun o tabi aiya? fi egbogi ajebidan pa ibiti o ndun o**

ELECTRIC Balm



## Fse Yaju Moto Lo Ara L'o‾mbo Si

Ọrọ yi koṣe fi ẹnu sọ ayafi ki enia fi oju ri iru itu ti nwọn nfi Kẹkẹ Ologere; (Bicycle) da nilẹ Ẹgbado.

Ninu irin-ajo mi ẹnu ọjọ mẹta yi nilẹ Ẹgbado, awọn ilu bi:- Ado-Odo, Ajilete, Oke - Ọdan, Tubẹ, Ipokia, Ijofin, Agọṣaṣa, Ibatẹfin, titi lọ de Ọja - Ọdan, niwaju Ilaro, ni mo nri ara meriri ti awọn ọmọ Ẹgbado nfi kẹkẹ da nipa wipe, ki nwọn fi Kẹkẹ ru ẹru ti Mọto kole gbe.

Eyiti o jẹ ohun iyalẹnu nla fun mi, iru ohun ti nko riri, on ni ọdọmọkunrin kan, ti o gbe abiyamọ kan ti o pọnmọ sẹhin si ẹhin Kẹkẹ rẹ, abiyamọ na tun ru ẹru lori, o fi ọwọ osi mu ibadi ẹniti o gun Kẹkẹ, o tun fi ọwọ ọtun wa ẹru rẹ mọri, lẹhinna, ẹniti o gun kẹkẹ papa tun ru ẹru ni alaiko fi ọwọ mu ẹru ti o ru, o si nwa Kẹkẹ rẹ yi lọ gẹgẹbi ẹniti ko gbe inkankan s'ori Kẹkẹ na rara.

Mo gba awọn ọmọ Iya wa wọnyi ni iyanju lati ma fi Ọmọlanke ko ẹru dipo Kẹkẹ Basikulu, nitori ẹsẹ mi ya ju mọto lọ, rara lo ma f'abọ si o.

Emi ni ọrẹ nyin,

Ọmọ-ọba Adeniran Adefarakan,
Alakoso Ile iṣẹ
Esan Kogbugun Service.
Lagos.

## Enito jin si koto, ko ara ehin logbon

KALABA Agbọ irohin wipe awọn agdẹ ara Kalaba meji kan ti nwọn ni oko Koko, ri eso Koko pupọ ka ninu oko wọn, nwọn si afẹ ki o gbẹ kia kia.

Nwọn da a sori a'an, nwọn si danọ mọ nidi nigbati o gbẹ nwọn gbe lọ fun tita. Nigbati awọn Aṣa'san rii ti odudu,nwọn bere bawo loṣe dudu, nwọn si ṣe alaye wipe nṣe ni nwọn yan a lori ina.

Agbọ pe inu bi awọn Aṣa'san na tobẹ ti nwọn gbe wọn lọ si Kotu, ọrọ na bi adajọ ninu wipe nwọn fẹ gba ẹna eru ni owo, oni ki nwọn lọ san ọgọrun Pọun tabi awọn oṣu mẹfa.

## Mrs Kuyinu D'ologbe

EBUTEMETTA. Agbọju'gbanu ni ti irohin iku ojiji ti a gbọ wipe, o ṣẹlẹ si Iyafin Caroline Fọlaṣade Kuyinu ninu ile Ọlọrun St. Jude lasiko ti nwọn nfi nkan p'ẹnu lẹhin isin.

A gbọ wipe Ologbe yi wa ninu awọn ti nwọn ngbe onjẹ fun awọn alejo ti o wa yọ ayọ orire ti ọmọ wa kan ti o ṣe orire bọ lati ilu oyinbo, ati wipe bi o ti ngbe onjẹ kiri yi, lojiji ni Ọlọjọ de si, o ṣubu lulẹ, nwọn fi mọto gbe lọ ni kiakia si Creek Hospital ibẹ ni titan gbe de si.

Njẹ iwọ Iyafin Caroline Kuyinu, Maṣe jẹ ọkun, maṣe jẹ ekolo; Ohun ti nwọn njẹ l'ajule ọrun Ni ko ma ba wọn jẹ sunre, sun,

## Eru Ta Oluwa Re L'eru

Awọn opitan sọ lasiko ti awọn oyinbo Panyan (Spanish) fi okun Eleke ṣe ile lati ma gba ibẹ wa ra ẹru ni ebute Idumagbo Ọkunrin kan ara isalẹ Eko ti a npe ni Obirikiti ni awọn Onisumọmi ka mọ ibiti o gbe nreko, ko ja, bẹni ko fa ijọgbọn, o wipe ki nwọn ṣe on jẹjẹ, on yio ma bawọn lọ,

Awọn Onisumọmi bere nibo nile rẹ wa, o dahun pe ni Idumagbo, nipa bayi nwọn mọ pe ara Eko ni bi nwọn ba si mu de Idumagbo awọn enia rẹ yio fija fun wọn, nitorina, nwọn niko niṣo ni Okun Eleke.

Nwọn ko mọ pe Obirikiti papaa iṣẹ owo ẹru nisẹ rẹ. On ko ngbe sunmọmi, ṣugbọn o nmu owo lọ ra ẹru lọja Ejinrin yio si wa ta a fun Panyan l'ebute Idumagbo. O gbọ ede Panyan daradara, nwọn si mọ ni Onibara, on na si mọ wọn.

Obirikiti ko yọnu rara, eyi ko jẹki ẹnikan fura si. Eeiti o mu Obirikiti lọ si Eleke, ko de ibẹ ri, ilẹ si ti ṣu ki nwọn to de ibẹ, ni awọn mejeji Obirikiti ati oluwa rẹ ba sun larin ọja.

Li oru, Obirikiti dide lọ ba onibara rẹ, o wi fun pe on mu ẹru kan to lagbara wa ta fun, ṣugbọn ẹru na le jọjọ, agbara egbogi ni on fi mu wa ihin, Panyan ni ko fi iyoku le on lọwọ, nwọn duna dura nwọn si gba owo, ni awọn igiripa ba mu koboko ati ẹwọn nwọn ba a, o nsun lọwọ. nwọn kan aba mọ lẹsẹ, ni nwọn ko patiyẹ bọ o. Bayi ni Obiriti ta pada wale.

Orin ti nwọn fi kii aye ko si lati kọrin na sihin yi.

OJOJO NṢE OGUN, ARA OGUN 'OLE

IJẸBU-IGBO. A gbọ wipe Oluwadi Oye Ọba Orimolusi ti Ijẹbu-Igbo, Ọgbẹni M. A. Macaulay, sọ ninu Afin Awujalẹ wipe on ri iwe Dọkita pe o fẹ si Alaiyeluwa Ọba Awujalẹ Ijẹbu-Ode diẹ nipa bẹ, ko ni le wa jẹri niwaju on.

Nitorina o lọ si Ijẹbu-Igbo lati gba ẹri l'ẹnu Oloye Odubanjọ Odutọla, Eletu Ifọrẹ ti a fun lagbara lati rọpo Ọba Awujalẹ.

Ki Oluwa fun Ọba ni alafia, piri l'o Olongo nji, A ki iba okunrun ẹiyẹ lori itẹ.

## AKIYESI PATAKI

**Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,**

LỌ SI:-

**18, Race Course Road,**

OKE—PADI, IBADAN.

E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun okan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—Ofe nigba gbogbo.


**Mo Gbadun Siga Pirate**




**PIRATE**

**Ni Siga To Dara**

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

25, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFẸ LAGOS"
P. O. Box 457 Phone 23370

VOL. VIII. NO 482. LAGOS, SATURDAY AUG, 25, 1956.


## Nibo Ni A Nlo?

Ọrọ akọle oke wosika wa ọsẹ yi ni a fiṣe ẹṣin asayan ọrọ wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa gẹgẹbi ibere nipa oniruru ohun iṣẹlẹ iyanu ti o nṣẹlẹ kakiri ilẹ Nigeria wa yi nisisiyi.

Ẹnikẹni ni yio jẹri si wipe o fẹrẹ jẹ ojojumọ ni a ngbọ irohin wipe wọn ji ọmọ gbe nihin, lọhun ati nibi gbogbo kakiri ilẹ Nigeria, papaa nilu Eko wa yi, ni asiko ti gbogbo wa ngbaruku ti awọn aṣiwaju Oṣe'lu wa lẹhin lati bọ ajaga silẹ, iyẹn ni wipe, ki a di ominira lati maṣe ilu wa funrawa.

Eyi koiti jẹbẹ ni awọn ọmọ ekee ko gbọdọ da ere ṣe l'ojude nibi wọn lai kosi abojuto gidi pẹlu wọn, ti ipania npeleke bi ehin Adepele, irufẹ iwa ọdaju, iwa ika ati iwa aiko ni ibẹru Ọlọrun l'ọkan awọn enia wọnyi mu enia ṣ'iyemeji lori gbogbo kita-dọnyin wa fun ominira. Nilu Eko wa yi, ni Monday ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu to kọja ni owọ tẹ Lamidi Alabi ara ilu Ilọrin ti on nikan ji ọmọ mẹta gbe lekanna. A ṣe irohin ẹjọ rẹ siwaju ive irohin wa ọsẹ yi.

Eyi ni a ri ti a nwi lọwọ ni a tun gbọ wipe giripa meji ara ilu Ibo tun ji ọmọkunrun kekere kan gbe ni Apapa, bẹrani ti ilu agbegbe Ibini, ti adajọ ti sa ni kọnko ẹwọn. Ki a ma ṣẹṣẹ tun sọ ti irohin ipania ti a ngbọ yika ilẹ Nigeria wa yi. Eyi ni ohun na ti o mu wa fiṣe ibẹrẹ wipe "Nibo ni a nlọ"? nitoripe ko tọ, kosi yẹ ki enia kuro ninu omi ti o nlọwọrọwọ, ki o lọ ko sinu omi ti nho yaya!.

Nitori bẹ, ali wosika wa yi ke si awọn aṣiwaju Oṣe'lu wa ki nwọn ba wa bojuto bi iwa aidara ti o ngb'ilẹ nilu wa yi yio tiṣe di ohun itan ti ako ni gburo iru rẹ mọ larin ilẹ Nigeria wa. O yẹ ki a mọ ibiti a nlọ ki a to bọ s'ọna.

## Alufa jo'na, o mbere Irungbon

Alufa kan ti irungbọn rẹ kun Pupọ wa ninu ile, o sun nigbati ina ṣẹlẹ ninu ile rẹ, ina ka alufa na mọ inu ile, kosi ri ọna gba jade. ko si awọn Panapana nilu na.

Gbogbo enia lo ndaro alufa yi, nigbati o ṣe, alufa na taji lati oju orun, ko si ri ọna gba jade efin ti kun inu ile. O wa woye pe bi ile yi ba wolu on mọlẹ, nṣe ni on yio jona raurau.

Bẹni alufa ba gbe iku ta o fi ori l'arin ina yi kọja, o si ṣubu si arin enia ni ode gbamgba. Gbogbo enia wa oki alufa na wipe, gbere rẹ! o ku ori re. Ọlọrun yọ ọ'

Iyawo alufa yi ti o ti sajade sare lọ sọdọ ọkọ rẹ o nṣe ọjọjọ rẹ, ko ri irungbọn rẹ. O bere wipe, Ha! irungbọn da? Alufa dahun wipe, irungbọn wo ni o mbere? kini ohun ti o kọkọ ṣe lau ninu ina, ni gbogbo enia ba bu sẹrin ha, ha, ha, he, he, he.

## Owe Yoruba

Ewu l'ogbo, irungbin l'agba, tubọmu l'afojudi. Iku owo l'o npa dọkọ-dọkọ iku ale l'o npa fale-fale afojudi l'o npa ọmọ kekere. Iku ogun l'o npa akin, iku odo l'o npomuwẹ, Iku ti yio p'ọdẹ mbẹ ninu apo' iku ti yio pagbẹ mbẹ lọrun ebe.


# ABOKI



JẸ AWOGBARUN to LOKIKI KA ILẸ ENIA DUDU.

AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JẸDIJẸDI, etc.

KOṢEFẸKU ni GBO-GBONṢE yi jẹ fun GBOGBO ILE ntori na RA IGO kan LONI Lọdọ:-

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,

Amun... Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN

E 21, Sabongeri, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205, Kumasi, Gold Coast.



MA FI

# BLUE BAND

SORI BREAD RẸ!




Blue Band dun pupọ lori bread sige, gbogbo enia li o fẹran rẹ! Blue Band ran awọn ọmọ wẹrẹ lọwọ lati dagba, o fun wọn ni ilera o si nran wọn lọwọ lati lagbara fun iṣẹ ṣiṣẹ. Gbogbo idile ti o ba njẹ Blue Band lojujumọ a ma gbadun rẹ lopọlọpọ.

BLUE BAND ni ki o ma fi din akara, didun re, adun yio si tupọ pọ si i!






BLUE BAND dun, o si aṣeni l'anfani

## Idibo Ile Hausa Kusi Dede

ZARIA- A gbọ irohin wipe Ọlọla Alakoso ijọba Oke-Ọya Sardauna Ṣokoto, ti ngbero ọjọ ti idibo na yio bọ si, ṣugbọn ẹnikẹni koi ti mọ ọjọ na gan.

A si gbọ wipe Sardauna yio ba awọn ogunna gbomgbo olori ẹgbẹ oṣ'elu ṣe ipade ni ọjọ Satide tokọja lati jiroro l'ori ọjọ ti nwọn yio fi idibo na si, ki o to sọ fun Gomina, Ọlọla Sir, Bryan Sharwood-Smith ki o fi aṣẹ si.

Gbogbo awọn ẹgbẹ oṣe'lu lorișirişi l'o nti gbaradi fun ikede idibo. ako si le sọ eyiti yio gba ijọba ṣugbọn ohun kan lo da ni loju wipe awọn ẹgbẹ alatako ijọba (Opposition Parties) nfẹ atunṣe atato ninu ọna ti wọn ngba dibo.

Boya a le gbọ ọjọ na laipẹ.

## Apelewon Nfi Ara Re Se Yeye.

IBADAN. Ninu kotu kan ni ilu Ibadan ọkunrin kan ọsọlẹ ni adajọ ṣa konko mọ lara nigbati o jẹbi ọrọ na niwaju adajọ.

Adajọ ni ko lọ si ẹwọn oṣu mẹsan, ki a si na a lẹgba mẹfa nidi rẹ.

Nigbati ọdaran Ọsọlẹ yi gbọ idajọ ti adajọ da fun yi, o rẹrin, o si wi fun adajọ wipe, kinla! on l'o wipe ki o lọ si oṣu mesan, mo fẹ sọ fun ọ wipe, ibẹ ko nṣe ajeji mi o digba mẹsan ti mo ti nlọ si ẹwọn o si nfi adajọ rẹrin akọ.

Adajọ dahun, o wi fun ọdaran na wipe ẹ wo ọbọ enia, o nfi ara rẹ ṣe yẹyẹ, ma rẹrin niṣo, ṣugbọn mo mọ wipe, nigbati nwọn ba fun ọ ni ẹgba mẹfa nidi rẹ. ẹrin ko o nijade lẹnu rẹ mọ. Ikoka alamọ kan o ni ṣile mẹta ni ọdaran na ji ninu ọgba Reluwe ki ọwọ to ba a.

**E ma ka Iwe Irohin ELETI-OFE Ki e Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin Aladun Yi Nigba-gbogbo.**



# OGBON ATI IMO

**Lati owo ESO IKOYI**

Ọkunrin kan ọlọgbọn ilé aiye ti a npe ni Sokirat (Socrate) on lo sọrọ yi wipe, ọpọlọpọ enia lo nfi ọwọ ara rẹ fa ibi ti o nde wa ba wọn, nwọn o si ma da Ọlọrun lẹbi wipe, On l'ẹniti o fi ṣe wọn. Ṣugbọn, ninu gbogbo ọgbọn aiye, ko si ọgbọn kan tabi imọ kan, ti o tayọ ọgbọn ati imọ nipa ara enia. Nitoripe odidi awọn ọgbọn orisi mẹta lo so mọ ara enia. (1) Ọgbọn inu, (2) Ọgbọn ara. [3] Ati ọgbọn ori.

Mo ni tanma wipe, t'ọkunrin, t'obinrin lo nka iwe irohin Eleti - Ọfẹ. Gẹgẹbi mo ti ṣetan nisisyi lati fi aṣiri diẹ han nipa awọn obinrin, bakanna ni mo le fi aṣiri ti ọkunrin papaa han, ṣugbọn ọrọ ọlọgbọn kan sọ wipe, obinrin ni Ọgbẹri, ọkunrin l'awo. Ko to suna ki obinrin mọ aṣiri kan nipa awa ọkunrin, nitoripe bi aiye ba tẹ wọn lọwọ, uwọn o jọ aiye na ni ajẹfọju. B'o le d'ogun, ko d'ogun, b'o le d'ọtẹ ko d'ọtẹ ojo p'ewe koko b'o le ya, k'o ya; ni orin ti awọn obinrin nkọ.

Ngo fi ẹnu ba diẹ n'pa aṣiri obinrin. Orisi m ẹ r i n ni ẹya awọn obinrin. -

1. Awọn ẹyà bí iru ododo kan [Flower] ti a np e ni Lotus.
2. Awọn obinrin to ma ṣwa jade wa lati ọrun.
3. Awọn obinrin ti ko lire, ti nwọn dabi ipasan.
4. Ati awọn ti nwọn santa bi Ajanaku.

AWỌN TO DABI ODODO LOTUS

Iru awọn obinrin ti a fi we itanna tabi Ododo Lotus yi ni, awọn obinrin ti o rẹwa, ti iri oju wọn dabi eyiti nwọn ran eju mọ enia, iru awọn obinrin bayi yio jẹ ẹniti o fẹran ẹsin jọjọ, awọn o si fẹran lati ma ṣe finni-finni. Nwọn o jẹ onigbọran si ọkọ wọn lẹnu, nwọn ko ni fẹ lati ma yaju si enia. Ilẹ ọkọ rẹ yio ma wa lọkan rẹ ni gbogbo igba.

Yio jẹ arẹwa gidigidi, iri oju rẹ yio si wu enia. Bi o ba nkọrin, ohun rẹ le dun, enikẹni ti iru obinrin bayi ba rẹrin si yio dabi ẹnipe ki obinrin na ma lọ mọ. Bi o ba nsọrọ, yio ma sọ ọ pẹlu ẹrin ati Ọyaya. Ati nigbati nwọn ba orin lo l'ode, yio dabi eyiti nyan tabi ti nwọn nṣe faari, obunkohun ti nwọn ba fi ẹnu ara wọn bere lọwọ ọkunrin ni nwọn o ri gba, nitori inu ọkunrin na nilati dun de gongo. Ohun kan ti ẹo fun ma ṣakiyesi lara iru awọn enia bẹ ni wipe, iho imu iru awọn obinrin bẹ yio kere. Iyoku di ọsẹ ti o mbọ.

Ẹnyin ọkawe wa, ẹniti o ba fẹ ki a tu aṣiri ti ọkunrin sita bayi, ki obinrin le rigbin wa gbe sire, ki o kọwe si Ẹsọ Ikoyi c/o Eleti Ọffẹ 28 Kọsọkọ St, Lagos. Awọn ti ko ba si fẹ bẹ ki o kọwe pẹlu, ki nwọn sọ kini idi rẹ ti nwọn fi fẹ ati ti nwọn ko fi fẹ.

---


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.**

A[illegible] ọmode ri orun sun daradara o dara fun otutu [illegible] i oris[illegible] arun miran ti o ma mba omode ja ni asi [illegible] Ọpọlọpọ abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo [illegible] so wipe ode[illegible] pupo fun awon omode

**ỌMỌRELA BABY MIXTURE**
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*
O wa Lọdọ:—

**COMMERCIAL MEDICINE STORES**
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS


---

## Owa Ilesha Ranse Ki Alafin

ILESHA. Si iyalẹnu gbogbo enia, ọba Ajimoko, Ọwa Ilesha Keji ranṣẹ wa ki Alafin titun Ladigbolu Keji nilu Ọyọ fun ti igbade rẹ.

Awọn ijoye to wa niwọnyi, Oloye Falode ati Oloye Lọrẹ ti o nṣe Babaẹgbẹ Kotu ọdarun.

Awọn iko na sọ wipe nigbati nwọn de Ọyọ, pẹkẹ ko mi ara wọn, alafia si gbẹlẹ. Lẹhin ti awọn ijoye na ki ọba Alafin titun tan, nwọn wa jiṣẹ Ọwa Ilesha fun, inu ọba si dun.

Awọn Imaro lo ma nkọrin bayi, nigbati ọtẹ-ba buṣe tan wipe:-

Ija pari, ija pari
Mo gbọ'filọ, l'alẹ ana
Olofofo, laṣọfra rẹ
Atẹyin oni, ṣondi-ṣondi
Ija pari, ija pari
Mo gbọ'filọ, lalẹ ana.

---

## Ijoba ri Simenti ni Abeokuta

ABẸOKUTA. Awọn olotu iṣẹ Portland Simẹnti ri oku'a Simẹnti pupa ni abule kan ti a pe ni Ẹrunbẹ nilẹ Ẹgba.

Aṣoju Sẹkiteri igbimọ ilẹ ẹgba sọ wipe lati abule Apena titi lọ de Erunbẹ nlẹ ayẹwo nitoripe nwọn rope okuta Simẹnti pọ nibẹ.

Ibiti nwọn kọkọ ri okuta Simẹnti ni abule Adapele leti ilu Ibeṣe nilẹ Ẹgbado.

Nwọn si nṣe ayẹwo rẹ lọwọ bi nwọn o ba ri okuta na rẹpẹtẹ.

---

## Ibon Sesi Pa Omode Kan

SHAGAMU. Ọkunrin kan ti a npe ni Bello ti o ngbe adugbo Ajina ni Ikorodu, lo di ibọn mọ ara kẹkẹ Basikulu rẹ, o si ngun u lọ si oko.

Lairo tẹlẹ ni okun ti nwọn fi di ibọn na tu bi o ti nlọ ni gẹrẹ-gẹrẹ oke kan, o bọ ṣubu lulẹ tẹlẹ-tẹlẹ lori akọ ni ibọn na wa, lo ba gba'na, gbogbo ọta inu ibọn na si ṣe ṣinra sinu igba aiya ọmọde kan, ti a ope ni Yẹkinni Apẹlogun, o si ku bamu-bamu.

Lọwọ jamba ati arinnako buruku, Oluwa rere gba wa.

---

## Ewon Odun Marun fun Aj'omogbe

BENIN. Ọkunrin kan ti a npe ni Dafidi ti o ti lọ ji ọmọ gbe nilu Ibini, ti awọn ọlọpa si ramu fun ẹsun gbọmọ-gbọmọ.

A gbọ wipe ọkunrin ti a npe ni Dafidi yi lọ ji ọmọ kan gbe nilu Igboko ẹba Ibini, nwọn si ju si ẹwọn ọdun marun pẹlu iṣẹ aṣe ṣẹ'badi. Ọkunrin yi ni ẹniti a kọkọ gburo rẹ pe o lọ ji ọmọ gbe, a ko iti gbọ ti awọn ti o ku.

---

## Polowo oja re sinu iwe irohin Eleti-Ofe


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS, PAINTS, DISTEMPERS SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**
20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
and NEW COURT ROAD, IBADAN.

## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7. Egerton Road, Lagos

## Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

JZ. 6000 - Joel Adeboye / Iba

" 6001 - Ile Eke St. Peter/ ) Rosey
Fija f'Ọlọrun Ja ) Show
" 6004 - Ekunsumi / ) Mambo
Oluwa Ipese ) Orch.

" 6002 - Isau Adewale / ) Ade-Ade
Adebakin ) & His
" 6005 - Ogunyemi / ) (Laja)
Ma Doju Tiwa ) Band.

" 6015 - Ojowu Binrin / ) Ayinde
Olajide ) Bakare &
Reis ) His

" 6016 - Gbo Adura Wa) (Juju)
/ Ayoola Shasanya) Band.

" 6031 - A Binu Eni / ) Baptist
Ajodun Wa De ) Church
" 6032 - Iba Fun Oluwa ) Choristers,
/ Gbogbo wa Alowo.) Yaba.

" 6033 - Igbo Irunmalẹ / ) Yesufu
) Olatunji &
Ayinde Gurudi) His (Sakara)
) Band.

" 6039 - Aduwosonu / ) Idowu Zan-
Obawefun ) clan & His
" 6040 - Agbo yi woro/) (Egun)
Soma Je Aduji) Band.



*Sold by all the best stores*

## "HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

---

### COME AND SEE THE DRAW FOR THE FIRST

# WESTERN REGION GOVERNMENT LOTTERY

**Which will be held at Mapo on Saturday, 25th August, 1956**

**From 4 p.m. Onwards**

THE PROCEEDINGS WILL BE OPENED BY

## The Hon. J. O. OSHUNTOKUN, (Minister of Finance)

**(In the event of rain the draw will take place in Mapo Hall)**

**1st Prize — £5,000**
**2nd Prize — £2,000**
**3rd Prize — £1,000**

## And many smaller prizes

**The Western Region Programme of the N.B.S. will broadcast the winning numbers between 4 p.m. and 6.30 p.m. and the names of the winners at 8 p.m.**




IRANSỌ to wulo fun IṢẸ ORIṢIRIṢI ati ALARABARA fun AṢỌ ỌKUNRIN ati ti OBINRIN. O DARA PUPỌ fun kiko oju ONINI ẸWU. O WA FUN TITA ni ỌGỌTA PỌUN pere fun ORI ati ẸSẸ.

Gbogbo IRIN IṢẸ RẸ lo ba ti SINGER mu.

## Baba rele o, ile lo lo tarara.

EKO. Ko si bo ti ri ni irohin iku Ọgbẹni Lawal Giwa ti o ngbe Kọsẹ Street, nilu yi. Ẹsẹ awọn alufa ati Alhadji pataki pataki lo pe awọn Jọnma Mọṣalaṣi Forobe peju-pesẹ. Awọn enia ti o lọ ṣe isin ikẹhin fun baba yi ti nwọn lọ situra rẹ si ile ikẹhin le ni ẹdẹgbẹjọ enia.

Awọn ọmọ ti oku na fi silẹ ni Ọgbẹni Akanbi Lawal, Tijani, Olowo-kokere ati omidan Lalonpe Lawal.

Diẹ ninu awọn gbajumọ ti o wa nibẹ ni, Lamọmu Forobe, Alhadji Ladi-meji, Alfa Labaika Bello, K. Ekunsunmi, Abdul Rahman Subair, S. Latunji, ati M. Ariyọ.

Ọba ko fi ori ji oku na, ki ẹhin baba dara si owo ati ọmọ.




ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹkun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d c.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores** 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute-Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.

## Awon Omode Kekeke Nfe Itoju

Nilu awọn Oyinbo, awọn ẹgbẹ alanu awọn ọmọ wẹwẹ kan wa ti a npe ni N.S.P.C.C.

Awọn ẹgbẹ yi ni awọn ti o nṣe abẹwo ile gbogbo kakiri, nitoripe ko nṣe gbogbo awọn oyinbo lo ni owo ti o si kọ pẹtẹsi, akuṣẹ paraku mbẹ ninu wọn.

Ọmọde kekeke meji kan wa, ọkan ọmọ ọdun mẹjọ, ekeji ọmọ ọdun meje Orukọ agba njẹ Peteru ekeji njẹ Johanu.

Awọn ẹgbẹ to nwọle kiri yi ba wọn ni aye ti ko dara, inu ile wọn tutu, nwọn ko si lesọ lọrun. Akuṣẹ ni obi awọn ọmọde na. Awọn ẹgbẹ yi ko awọn ọmọde na lọ ṣe itọju. A gbọ wipe ara awọn ọmọ na tiyi pada, oju wọn si rẹwa.

"Itọju ni oye abẹrẹ" owe Yoruba ni, bi a ba nṣe itọju awọn ọmọ wẹwẹ daradara, abiku yio dinku pupọ.




Ibikibi ti ami olokiki KINIUM-FILLIPI ba wa o jẹ ifọwọsọya fun 'AGBARA alailẹgbẹ ati ẹwa ti a fi ṣe iṣẹ.

Awọn irin-arẹ Basikulu FILLIPI (frames and forks) ni awọn akanṣe iṣẹ ti a ṣe sinu wọn biotilejepe ko han sode nwọn fi agbara alope si ibito yẹ. Iwadi iṣẹ-ona to le ni ọgọta-ọdun lo fun wa ni igboiya lati wipe KINIUM-FILLIPI ni yio ma gbori lọwọ gbogbo won.

SI ILE'ṢE

PHILLIPS CYCLES LIMITED, BIRMINGHAM, ENGLAND

ORUKỌ:-

ADUGBO ILE:-

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 2331